# Volta

# Yoruba / Yorùbá

Richard Berengarten

Tí Kọla Tubọsun túmọ sí Yorùbá
Translated from Yoruba by Kọla Tubọsun

## Volta

*…báyìí tilẹ nsú lọ…*

Ọba òòrùn, abẹẹkẹ pupa, ọba owó eyo ọjọ,
O fọwọ kàn mí, àwọ mi sì dẹyin ojú,
ẹyìn mi bíi isàn ìríran, ara mi sì mìtìtì,
ó n se mí ní kàyééfì ibú wúrà tí o n dà
sórí òkun yìí, àtilú, o sì fọ mi lójú.
Níbí yìí ni àwọn ìlà elétò wà nígbàkanrí –
Mo sì mọ wipe wọn dúró síbẹ síi –
Àti àwọn ilé àti àwọn ọnà ìrìnsẹ, èyí tó jẹ ti ilú mìíràn,
Kíi se eléyìí tí o ti yípadà pátápátá.

A n rìn lọ lẹbàá omi. Ọkọ ojú omi àsálẹ
Ti àwọn apẹja ti setán láti jade lọ,
ọkọ n mì tìti, àtùpà kúùfín nínú awà,
gbogbo ilú sì ti jade lọ fún ìrìn ìrọlẹ,
àwọn olólùfẹ n múra wọn lọwọ, awọn ọdọmọkùnrin n mìlẹngbẹ,
àwọn ìyá àti bàbá, àwọn omọdé n jẹun ẹlẹrìndòdò,
àwọn arúgbó n woran láti orí tábílì lórí pèpéle ní gbangba,
àwọn òkè dúdú yìí n súnmọ síi, gẹgẹ bíi àwọn ẹranko jẹjẹ.

Iná dídùn tó n tàn lásàlẹ, to tàn yíká àwọn òkè àti etí omi,
Apá rẹ kàn mí báyìí, bí eni pé ó seesì se bẹẹ ni,
Gẹgẹ bíi ìfarakàn ọdọmọbìnrin yìí tó n rìn lẹgbẹẹ mi
Pẹlú ètè nlá, ìrìn ẹsẹ kékèké, tó sì n yí bírípo,
Irun dúdú tó dà sẹyìn, ọfun ẹlẹgẹ àt'èjìká
Dídán bí àwọ irin, tí ojú rẹ bí igi olífì sì n rẹrìín.
Mo mu ọ, ìwọ ìmọlẹ, bí ọtíi wáìnì, bí orin,
Gẹgẹ bí àwọn ẹni ìsaájú rẹ ti mu ọ fún ẹgbẹrún ọdún.

Ìlú tó lu kára bí ajere. Orúkọ rẹ ni *Elefitaria*,
Sùgbọn àwọn ojú egbò rẹ jẹ oun dúdú fún ojú rè,
Síbẹ, ní wákàtí yìí tí ìmọlẹ àti àwọn ìtansán rè
Nseré jẹjẹ lójúu rẹ bí ọrọ tabí orin,
Tirẹ ni ẹtọ ọjọ pípẹ láti rìn ní ẹbá omi yìí
Gẹgẹ bí irinsẹ àti atọnà fún ìmọlẹ rẹ
Tó n gbàá sínú kanga ojú jíjìn rè,
Àti tirẹ, òminira àtàtà, láti tẹ ọ mọlẹ gẹgẹ bí oníjó.

Ìrọlẹ àtàta, ọmọ àkàimọye ẹgbẹrún ọdún,
Olóhùn orin gooro tó mọ lóló, dídára gẹgẹ bí obìnrin yìí,
Báwo ni èmi ò se ní bú ọlá fún ore ọfẹ tí o dà
Ilú yìí àti àwọn ènìyàn rẹ sí, ìtì kan
tó n mọ gbogbo oun tó bá fọwọ kàn, gbogbo ayé?

Èmi ti di ẹrú rẹ, bí kò bá n se ọmọ rẹ.
Àti láti mu ọ lámuyó, àmukún, Ngo kún
Gbogb ihò pẹlú mímọlẹ rẹ, òminira rè.

Richard Berengarten

Tí Kọla Tubọsun túmọ sí Yorùbá
Translated from Yoruba by Kọla Tubọsun

interLitQ.org